# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 558 WEDNESDAY MARCH 18, 1964 (2D)


## Egungun Kan Na Ọlọpa ni Ana Sare

IJẸBU-ODE:- Ọrọ kọ siso ni ọjọ Ọjọ Bọ tiṣe ọjọ kọkanla oṣu yi, nigbati awọn isọwọ Egungun (Ara Ọrun) ti nwọn bẹrẹ si fi ẹgba atori wọn dara si ọlọpa kan lara ti ọkunrin na si jo ajo wọlẹ lara ode gbangba.

Agbọ wipe ọlọpa yi ko wọ aṣọ iṣẹ rẹ. Bi ẹgba atori awọn Egungun yi ti nto si ọlọpa yi lara, were o fi ọgbọn bọ bata rẹ silẹ, o tun ju fila rẹ silẹ, ni o ba yọ bọrọ, o si fi ẹsẹ fẹ ẹ. Bi ẹniti o si yan ti ko duro gba ọbẹ.

Onirohin wa sọ fun wa wipe Ọlọpa na Rafiu Ọbatolu wọ ẹwu sulia ni irọlẹ ọjọ na ni o ba yara lọ si Ile ololufẹ rẹ, ni o ba bọ ni ọwọ awọn Egungun na.

Bi awọn Egungun na ti foju kan a n nwọn ba kesi pe ki o si fila rẹ ki o tun bọ bata ẹsẹ rẹ, ṣugbọn o ko da wọn lohun rara.

Bayi ni awọn Egungun yi ba ṣuru bo o ti nwọn si a a ni ana sare.

Onirohin wa fi ye wipe awọn Ọlọpa ti mu ẹnikan ti nwọn lero pe o le ṣe iranlọwọ fun awọn lati ri egungun ti o na ọlọpa ni ara si fila sọnu. Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹ o maa bọ o.

### Balewa Sọ Pe:

# OHUNTI MO BA WI NI ABE GE, KO SI ẸNITI O LE YI PADA

## Awuyewuye Abayọri Eto Ikania D'opin

EKO:- Kẹkẹ pama gbogbo awọn ọmọ ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria lẹnu to bẹ gẹẹ ti gbogbo ile Igbimọ na fi palọlọ nigbati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ ijọba Naijiria fi nsọ fun Ijoko ile Igbimọ wipe, On ti gba abayọri eto ikania ti o jade laipẹ yi kẹkẹ ko gbọdọ gbin, bẹni ko si ẹniti ole yi ipinnu on pada lori eto na.

Oniwe irohin wa Ejingboro ti olọ si ile igbimọ na fi ye wa wipe, gbogbo awọn ọmọ ile igbimọ na ni nwọn patẹwọ ti nwọn si ho gee bi Alhaji Balewa ti lẹ sọrọ, nigbati osi sọrọ tan, ko si ẹniti osọrọ leri ọrọ na

Lẹhinti Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọrọ rẹ lori abayọri eto ikania na tan, ti ẹnikẹni ko si sọrọ leri ọrọ na, ni oba jade ninu ile igbimọ na, o si awọn yoku silẹ lati maa ba awọn iṣẹ miran lọ.

### ỌRỌ IKẸHIN

Alhaji Abubakar ṣe alaye fun ile Igbimọ na wipe, eyi ni yio jẹ ọrọ ikẹhin fun On lori abayọri eto ikania, On ko si ni sọ ohunkohun lori rẹ mọ lẹhin eyi.

Eyi ni Ọrọ ti Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọ.

"Mo fẹ lati sọ fun gbogbo Minista, akọwe ati gbogbo ẹnyin Ọmọ Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria wipe Igbimọ Apapọ ti o ngmojuto eto ikania, eyiti nyan lati Ipinlẹ kọkọkan, eyiti mo yan lẹhinti abayọri eto ikania ti Ọdun 1962 fẹ da rogbodiyan silẹ, nwọn ti tun awọn enia Orilẹ-ede yi ka nigba keji.

Igbimọ na ti fun mi ni abayọri eto na, nwọn si ti sọ iye ti awọn enia orilẹ-ede yi jẹ ninu eto ikania ti igbakeji eyiti nwọn tun ka ninu Ọdun 1963

Mo fẹ sọ fun nyin wipe, gẹgẹbi Alakoso Ijọba Orilẹ ede Naijiria Alailọba, mo ti gba abayọri eto ikania



Alhaji Abubakar Balewa

na, emo si gba wipe awọn enia na ṣiṣẹ wọn pẹlu otitọ inu ati ododo.

Mo si ti gba eto na ki o to di wipe, awọn iwe irohin tẹ jade.

Ṣugbọn mofẹ sọ fun nyin wipe, emi ati awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ kọọkan yio ṣe ipade lati fikunlukun, ki a si jiroro lori Ọrọ na, ati awọn nkan miran ti o ba fẹ amojuto fun Orilẹ-ede yi.

"Ni ipari, mo fẹ fi ye gbogbo Ile pe, ohunti mo ba wi lori abayọri eto ikania yi, ko si ẹniti o gbọdọ yi i pada."

Onirohin wa fi ye wa wipe gbogbo awọn Minista ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni nwọn nwo ara wọn loju nigbati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa nsọrọ, ṣugbọn ko si ẹniti o wukọ ninu wọn.

Nigbati Alhaji Abubakar sọrọ rẹ tan, o joko fun igba die, nigbati kẹkẹ ko si le gbin, ti ẹnikẹni ko sọrọ, ni nwọn ba mu ọrọ miran sọ, Alhaji Abubakar si jade lọ si ita.

### ITẸWOGBA

Irohin fi ye wa wipe, Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti gba abayọri eto ikania na ni ọsẹ keji ti eto na jade

Gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni Kaduna ni nwọn ti gba wipe, lori iyeti nwọn pe awọn enia Ipinlẹ na ni nwọn o maa ṣe eto iṣẹ aje fun Ipinlẹ na, eyi yio si bẹrẹ lẹsẹkẹsẹ ti abayọri eto na ti jade.

Alhaji Ahmadu Bello Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi wipe ki nwọn o maṣe yi pada kuro lori ipinnu wọn.

A gbọ wipe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti Oloye Akintọla nṣe akoso rẹ ti gba abayọri eto ikania na lẹsẹkẹsẹ ti o ti jade.

Agbọrọsọ Ijọba na sọ fun oniwe irohin wa Ejingboro ni Ibadan lasiko na wipe, abayọri eto ikania iṣe ohun ti o kan Ijọba Ipinlẹ o ni lọwọ Apapọ Ijọba Naijiria ni eto atikọ ati atigba wa.

O ni bi awọn kọ, bi awọn si gba, ohun ti Apapọ Ijọba ba wi lai rẹ ni abẹ ge.

Ṣugbọn Ijọba Ipinlẹ Ila

(WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## Awọn Iganmuṣe PỌ Ni Mushin

Olotu ẹ jowọ ẹ gba mi laye diẹ ninu iwe nyin ti njade lojumọ lati ba Ijọba Amugbalẹgbẹ ti ilu Mushin ki nwọn ran wa lọwọ lati se ofin ti yio jẹ ki awọn igamushe tan ni ilu Mushin. Nwọn fin iya jẹ awọn enia paapa alejo to ba kọ sesẹ de Mushin.

Awọn iganmuṣe na to mẹfa si mẹjọ awọn o ma lu agogo, nwọn yio ma korin nwọn ni ẹwa mu sara ẹniti o ba duro ti nworan, nwọn tun ma jo nwọn otun ma korin.

Bi awọn ero ba po, nwọn yio ko ara wọn mọ ero t i nworan, nwọn yio fun gbogbo e n i a ni iwe kan ti nwọn di kuduru.

Nwọn yio kọkọ gba ti ọwọ arawọn, nwọn n w ọ n yi o pe, ogede bi wọn ba ti fun iwe na nwọn le b a ago isomọwọ tabi owo pepa bi ponun merin.

Bi o ba jẹ ago, nwọn yio bere sile mẹwa, bi o ba ti san sile mẹwa tan ti nwọn fẹ fun o ni ago, lọgan ni ago na yio ba parẹ patapata,

*Bi* o ba si jẹ owo pepa, nwọn yio wipe fun awọn ni ponun kan pere ki o si g b a ponun merin, bi nwọn ba ti gba o w o ọ w ọ tirẹ bi o ba ti f ẹ tẹwọ gba owo na ni owo na yio ba pora patapata

Iwa ti nwọu nhu niyi, nibiti o ti npariwo ni nwọn yio ti tuka yanga.

Emi ni,
T. A. POPOỌLA
Mushin

Le gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati ba awọn oṣelu wa sọrọ ni Ipinlẹ Iwo-orun lori ẹgbẹ titun ti wọn sẹsẹ da sile laipe yi ti ami wọn jẹ ọwọ

Mo bẹ awọn aṣoju wa ni iwọ Orun Naijiria pe wọn jawọ nidi do nitoripe ọmọ kekere lo nta, loni Ọlọmọkulumbu ọla Alakuko ati bẹẹbẹ lọ, o yẹ ki ẹ jawọ ninu iwa ti ko dara yi.

Awa ọmọ Yoruba ni ẹ nfi iwa jati jati nyin yi rẹ lara, a ko le sọrọ larin Ibo mọ bẹna ni a ko ni ẹnu ọrọ larin awọn Hausa, esi ti ofun wa, ni pe Yoruba ko ni lari Awa ko mọ ju owo lọ

Bẹni gbogbo wa ki a ti feran owo ju ọmọ iya wa lo, ẹnyin na ni ẹ nba wa jẹ ẹnyin onselu wa ti ẹ nsa kiri bi ẹiyẹ .

Mo fi Ọlọrun bẹ nyin, ẹ mọ fi ti nyin rẹ wa lara mọ, bi oṣelu ko ko ba sese ẹ koni si oko nyin Olotu ajinde ara yio ma *jẹ* o

Emi ni,
J.O.A Araoyẹ
Ilobu

## Kini Ẹ wi O?

Inu mi yio dun pupọ bi olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ lati ba awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun sọ atata ọrọ, nitoripe o nbọ, nbọ awọn ni nwọn dẹlẹde ni aiye atijọ, ni o ode toni oju ni nwọn nmuto. Olukaluku ẹwẹ n/o si nṣe ki iyọ dun ti on.

Lati igbati Ijọba ti gbe eto enia kika jade ni gbogbo Ijọba ati enia ko fọkan balẹ onikuluku si nsọ nkan ti o wa lọkan rẹ jade fun araiye gbọ.

Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni rara iye kan ni awọn nwọn ni awọn gba igbe jade enia kika tọwọ tẹsẹ.

Ijọba Ila-Orun bafi ake kori awọn ni rara o a w ọ n e n i a, Ipinlẹ Ariwa ko pọ to i y e ti nwọn pe, Lẹsẹkẹsẹ ni Olori ijọba Ipinlẹ Ila-Orun babu m ọ awọn enia ti o wa ni Ipinlẹ Ila-Orun.

Kakaki Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun na bu mọ tirẹ, nwọn ko tilẹ r o ẹhin ọla wo ti nwọn gba abajade enia kika n a. Gbogbo nkan to ṣe awọn enia w a ko ju owo lọ, bẹni bi enia baku k o n i mu ọnini kan lọ sọrun. Ẹjẹ ki aronu.

Mo dupẹ olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,
LIADI KARIMU
Ọyọ.

## Ajegunlẹ Nfẹ Atunṣe

Ẹ jọwọ ẹ gba mi ni a y e diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati kesi kesi Ijọba Ibilẹ Ajegunlẹ ki wọn o sanu wa lati fun wa ni awọn nkan meremere bi o ti se wa ni ilu miran

Iya nla ni onjẹ ki a to ri omi mu, bẹni omi ṣe pataki lara awọn ẹda, paapa isẹ ti omi nṣe ninu igbesi aiye enia ko se fi ẹnu sọ, awọn Yoruba ni o mọ kọ orin kan pe, ẹnikan ki ba omi sọta, ara kini omi ṣe, omi ni abuwẹ, omi ni abamu.

Iya ti o njẹ wa ni yẹn, bẹni lile ni nwọn nle wa mu nitori owo ori, ẹniti ko ni iṣẹ lọwọ tulasi ni o ni lati san owo ori ni. Bi a ba san owo ori tan, ẹ o tun ni ṣe nkan ti a nfẹ fun wa rara,

Nitorina mo fi Ọlọrun bẹ nyin ẹ fun wa ni omi ti a o mọ mu, ati awọn nkan miran bi mamamana ni ita gbangba bi ti Eko. Ibadan ati awọn ilu nlanla yio ku.

Olotu inu mi dun pupọ fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ,

Emi ni,
JAMES ADIO
Ajegunlẹ

## Ewo ni Ẹgbẹ Ọlọwọ

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba

## Ema a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ


## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
Ẹnikẹniti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INA-KUNA. KI *O* LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ un wa ni rere ti aiye ati t'orun Oluwa wa, ki o siso wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Oluforiji [illegible] Amin.

### "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ni oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA.
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*
MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan


## Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


EGBOGI JAMỌN-:-
## 'GLUTAMONE'
TI O DABI IṢỌYE

Egbogi yi jẹ oogun pataki ti nwọn ṣẹṣẹ ṣe fun anfani awọn ti nwọn saba maa gbagbe ọrọ tabi ranti ẹkọ ti nwọn ba kọ wọn ni ile-iwe.

O tun wulo fun awọn ti iye wọn koji perepere to lati ranti awọn ohun si ọkan. Papa julọ, o dara fun awọn onişowo, awọn olukọ, awọn ọmọ ile-iwe ati fun agbalagba ti o fẹ dabi ẹni pe ko ni iye ninu ma.

Egbogi yi tun wulo fun awọn "Isan ara" to o fe dabi ẹnipe ko mu osiri to tabi ki arẹ ma nu ni nigba gbogbo. Tabi awọn ti ima saba rẹ ti oju oroju ma nyọ lẹnu.

Egbogi yi wa lati sọ iye rẹ ji perepere ti o s ma ranti gbogbo awọn ohun ti o ti kọ fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin yio wa dabi ẹnipe o sẹsẹ kọ wọn ni.

Egbogi yi wulo fun awọn ọmọ ile-iwe ni asiko idanwo wọn lati le mu wọn ranti gbogbo ohun ti wọn ti kọ yekeyeke.

O yẹ ki egbogi yi wa lọwọ awọn akẹkọ, Onisowo, onisẹowo, tọmọde tagba ni owulo fun.

Oni lowo ogun isọye ti o jẹ ti osi daju haouhanu Bere ni sọbu awọn:-

Waterloon Mdicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)
Adedun Chemist,
4, Wakeman Street,
Yaba.
Iṣẹ Olodumare Dispensary,
Oke-Bọla, IBADAN.

# Işe Ti Owo Nşe

Lati Ọwọ AFỌLABI ALABI

Aje toto, aje ti ns'agba dewe
On na lo nmu ọmọde gori ipo agba
Lo tun nsọ Agbalagba d'ọmọde
Ni Igọ are ate Igbẹsa to nlọ yawo
To Pajọsẹ ọmọde ni baba
To pe ẹniti ko to ni burọda
Aje t-to, aje ẹgbọn lotitọ
Aje toto, aje ti nsagba dewe

Aje toto, Iba ki nlowo lọwọ
Oyinbo to gori Okun ati ọsa
Sowo lole wọn jade. Ape kanuko
Owo agba lẹhin enia
Ato bani ko iya lọjọ to buru
Onikumọ edun t i nle ọmọ ko gbo
Toto mo juba eleti girrinrin
Ẹniti o juba rẹ, ko ni tosi mọ.

## ỌMỌ YẸLE

Bọmọde juba fagba, ki iba sẹ
Aje toto, aje ti nsagba dewe
Aje toto, iba te, wa ba mi gbe
Ọmọ lo şe ibikeji ipo enia
Ori ko jẹ nlọmọ laiye mi
Ọmọ to gbọn, to mọ lakaye
Ọmọ to mọ sẹhin bi mo rele
Bo jẹ ọmọ kan nko pasan laiye.

Bo nşe fuja aiye a mẹnu si
Ẹniti ọmọ ba sin lo bimọ
Ẹniti pupọ mọ seregun
Ori ko jẹ ki nbimọ atata
Ọmọ to mọ sẹhin bi mo ba rele.

## ★ YE IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Ọjọ oni dara fun ọ la ti şe eto fun ọjọ iwaju, mase binu si ẹnikẹni.

PISCES (Feb 19 - March 20) Awọn ohunti o ko lero tẹlẹ ni yio ma a yọju si ọ loni, o si ri nkan gba ju loni.

ARIES (March 21 - April 19) Şe pẹlẹpẹlẹ pẹlu are şişe loni ki awọn kan o ma ba şe jamba fun ọ.

TA RUS (April 20- May 20) Ko si ohun ti o le şe loni ju ki o mojuto isẹ ara rẹ lọ ki o si ma sọrọ pẹlẹpẹlẹ titi ile yio fi şu

GEMINI (May 21 - June 21) Ti o ba lọ si irinajo loni o şe alabapade awọn ọrẹ ati ojulumọ ti nwọn o şe iranlọwọ fun ọ.

CA CER (June 22 - July 22) O şẹşẹ berẹ igbesi aiye titun nisisiyi, ma kiyesi ohun ti o ma a şe dada.

LEO (July 23-Aug 22) O le jowu ju, şọra pẹlu ọrọ ẹnu rẹ, si sunmọ awọn ọrẹ rẹ loni

VIRGO (Aug 23 - Sept 23) Ifẹ olufẹ rẹ nfa siọ, bi o ba si ba tage loni o daju pe nkan o şeru re.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Maşe ohunkohun ti o ba le şe loni sile di ọla. Akoko ko duro de ẹnikan ọjọ nlọ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Işẹ pupọ wa fun ọ loni lati şe oju ọjọ si dara fun ọ lati te siwaju

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Ara rẹ yio maa ya lati şişe loni, şugbọn şọra pẹlu aisan ojiji.

CAPRICORN Dec 22 - Jan 19) O gbọ irohin ayọ kan loni ki ilẹ to şu, ọjọ oni si dara ki yio si nkan, ilọsiwaju wa fun ọ lọjọ iwaju.


# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE FUN EGBOGI



## "CYCLEVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ o si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe şe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amod ti o buru ni pataki fun Ọkuarin ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma powo wọn fun iwosan rẹ şugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le şe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun berẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o berẹ nipa aiko ma pe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna şẹlu lojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu, pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Şuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni thẹ? Bi o nyọ jade ninu omusu, tabi ti o ba nmu eje wa lehin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "GYCLOVFN" ti awọn Oyinbo Jamani şẹşẹ wa idi rẹ kao ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹpatapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbgi oi wu igboro ilu Naijirialakejado. Bere rẹ ni:—

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)
(2) Adedun Chemist
'þ Wakeman Street Yaba


## AKIYESI

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IŞORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI: —WOLI ORIOLOWO AKINDELE ADEAGA COMPOUND RILE—ILUGUN VIA—IBADAN


# BI O BA NI Iwe—Titẹ

*FUN*

**Lilo nibi işẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

*ATI*

**IWE Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IŞẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NBGA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Danwa wc lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ*

# Iranti Iku Oloye Alapinni Oro

Lati owo:— J. O. LAWODE Oro.

Alapinni, o ku ni 17.1.64, lesekese to dake, ni Oloye Bale, Oro sare wa si Offa lati PHONE si omo re ogbeni P. Fapanule, ati ogbeni M. Fapannle 'towa ni EKO' lese kan na ni Ogbeni P. Fapannle da won lohun wipe ki won da oku na duro de on, on pelu posi ni yio de.



OLOGBE OLOYE ALAPINNI, ORO

P. Fapannle Sare lo ra posi olowo iyebiye on gbe moto re No L D 3913 si oju ona, awon egbe re na gbe moto ti nwon na pelu won de Oro ni ojo kanna

Nigbatodi ojo 18. 1: 64 ni dede ago mewa aro ojo na gegebi eti se n o pe esin Aguda ni won Rev. Father oga to wa ni Oro . O se isin Ikehin fun oku n a. Lese kanna ni ogbeni P. Fapanle ati I. Fapanle, ati awon egbe re to ba lo pada si Eko, won de Eko ni dede agogo mesan ale, nwon si ba opolopo enia ni ile won ti nwon njo ti nwon nmu. ogbeni P. Fapannle ati M. Fapannle nwon se inawo oku ni Eko ni ojo 21: 1: 64 ni No. 56 Idoluwo Street, Lagos nwon na wabiwosi Owo ni ojo na.

O tun di ojo 25: 1: 64 nwon tun lo se inawo. Isinku ni Oro

Awon enia ti o ba lo si Oro lo se inawo na ni Ogbeni J. Ogunjolu Ogbeni M Oyewumi, J. Lawal, Ogbeni Ogbeni A. Adekoye, Ogbeni M. Awoyale, Ogbeni P Afolabi Ogbeni A Ode Ogbeni B. Odunlami Ogbeni S.B, Togun Ogbeni K.O Fatoye Ogbeni A. A Awodiji ati opolopo enia.

Awon Egbe St Joseph to ba Michael Fapannle lo si Oro Ogbeni Kadiri Ogbeni J. Adedoyin Ogbeni I'Awo leye Ogbeni M. oyejola Ogbeni J. Adedoyin Ogbeni A. Abeni S Olidimeji Ogbeni M. Oyeyipo Ogbeni J. Atunde J Awo, P, Afolabi ati opolopo ti a ko le daruko.

Oloye Alapinni omo Ologbojo, omo Adegun se lawo, bo dele o kile, bo de ona o ki ero ona o ba wa ki awon to ti je Oluwa ni pe, o ki Oloye Asanlu, emi Duntoye omi ni kafolawe oki aran okoko asola oko anidi ni won esin, orun re o

AH ! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

**FORESTER CENTENARY HALL**

**22, Odunlami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Odun Ileya) at 6 p. m. till dawn.**

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B E. Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tikets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamebose Street, Irohin Imole Offices, Wemimo Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta.

**KERE O! AKIYESI PATAKI**

Awa na le yeti wipe Ojulowo kauhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Asara Ghana) pelu, meji re ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri ilu Naijiria.




Irohin Kakiri Igboro Ilu

Be na ni eweni igboro Ilu Eko. Irohin ti owa lenu bogbo en omode t'agba ni asiko yi ti nwon si fi se oro ati orin larin ara won ni ipa Egbogi Jaia i olokiki yi ti nwon ope ni LEOPILLS n Imoran awon Dokita Oyinbo ti awon nse iwadi Egbogi LEOPILL yi kan so wipe bio ti lagbara to ati o je Ojulowo giriki ati atama tase fun awon "JEDIJEDI" bi o ti wu ki ojo re pe to bena ni awon le tun fi owo soya tabi seleri fun gbogbo awon ti amodi tabi Iju, tabi Igbe sise, tabi aiko ri igbonse dede. Inu rirun nigbakugba ara wiwo, Esanri, ehin didun. Oju sisan, tabi aiko riran kedere kodoro buruku lara, Osinu Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pelu "Wipe" nwon yio ri alafia ni kiakia ti owon ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun eje se lara enia nipa siso di otun pat

ŞE IRANT PE ALAFIA L'OGUN ORO. IJAFARA SI LEWU (POSTAGE 1/9d)

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS: Igo nla şile mefa abo (6/6) pere ni Igo kekere şile meta abo (3/6) pere ni Bere Ojulowo Egbogi miran fun orişirişi Amodi ti o ba fe ni Şobu awon:

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 558 WEDNESDAY, MARCH 18, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti nwọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹnití o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

OLOTU

# INA JO ILE KAN NI FALỌMỌ RAU—RAU

EKO:— Gbogbo ilu lo gbọjikan fun ariwo nla, ti awọn enia si bẹrẹsi sare dide lati Ori ẹni wọn ni Oru Ọjọ Ọjọ'Ru ti iṣe Ọjọ kọkanla Oṣu yi nigbati ina nla bẹrẹsi ijo ile kan ni Falọmọ, adugbo kan ni ọna Ọbalende.

Irohin kan fi ye wa wipe ẹnikan ri o gbagbe fi ina atupa silẹ ni o ba sun lọ, nigbati o di ni oru ni atupa na ba gbina ti o fi jo gbogbo igi ti wọn fi ṣe opo ile ko si si ẹniti o ta ji titi ina na fi ran mọ ara igi ile.

Bẹni ina yi fi ran mọ gbogbo ile ti o wa di ohun nla ti apa ẹnikankan ko fi ka ma.

Obinrin kan ni a gbọ pe o ki gbe ti gbogbo awọn ara adugbo yoku fi taji, on na ti ile gbagbe ọmọ rẹ ti iṣe ọmọ oṣu kan silẹ.

Laipẹ agbọ pe, were ni nwọn lọ gbe ọmọde na jade ninu ile ti nwọn si gbe lọ si ile iwosan.

Ọpọlọpọ ni awọn ti ina na ba ohun ini wọn jẹ ti nwọn di alaini ibugbe mọ bayi.


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

**RICHALET**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Tatambulu s Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu.

Waterl oon Mdicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)



LATI OJU EWE KINNI


Orun Naijiria eyi ti Dọkita Michael Okpara aṣe Alakoso rẹ, ti kọ abayọri eto ikania na.

Irohin fi ye wa wipe, ẹgbẹ sọ wipe awọn ko fẹ gba ẹgbẹ Olomi ṣe Apapọ Ijọba mọ nitori abayọri eto ikania yi.

Dọkita Okpara Olori ẹgbẹ Alakukọ ti sọ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ wipe ki nwọn fi aye iṣẹ Minista wọn silẹ ninu Ilẹ Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria ti ọrọ abayọri jeto ikania na ba wa siwaju joko Ile Igbimọ na.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti nwọn wa ni aye Minista ko fẹ ti aye Ministi wọn silẹ, nitoripe ni oṣu kẹwa ọdun yi ni nwọn o tu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba ka, ti nwọ o si di ibo atundi miran si Ile Igbimọ na.

Nigbati ọrọ ti Dọkita Okpara kan Alhaji Balewa ni o ba fi kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa ni aye Minista pe ki nwọn gba abayọri eto na tabi ki nwọn fi aye iṣẹ Minista nwọn silẹ

Agbọ wipe awọn kan ti nlọ ba awọn ọmọ ẹgbẹ olomi ninu ile wọn ni opin ọsẹ ti okọja yi wipe ki nwọn mase mu ọrọ abayọri eto ikania na wa si ijoko ile igbimọ, ki o ma ba ṣẹ da rogbodiyan ti o le ba asepọ ẹgbẹ mejeeji jẹ.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, boya imọran yi ni Alhaji Abubakar tẹle ti ofi sọ wipe on gbe abayọri eto ikania na lọ si ipade awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ kọọkan eyiti nwọn ose lai ẹ yi.

Bi nwọn ba ti tun sọ si ẹ o maa gbọ o.

## Akiyesi Pataki

A nfẹ Aṣoju ni awọn ilu wọnyi, Ọtta Abẹokuta, Ibadan, Ilugun, Ololo, Agbọwa,-Iko si Ikorodu, Ọyọ, Awẹ, Ilesha, Ẹdẹ, Ikirun, Iwo Shaki Iṣẹyin, Tede, Oke-Amu, Iganna, Omu-Aran Ilorin Ajaṣẹ-Ipọ, Ifọ, Abalabi, Idọgọ.

Kọwe si
Circulation Manager.
16, Gbamgbose Street,
Lagos.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495 Phone 21985
Editor : TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S.Grammar School) Bariga Yab Lagos 18/3/64